**IMỌLẸ ODODO**

Ebun ọfẹ 12s. 6d. fun Musulumi Ododo IWE IMỌLẸ ODODO ti o ni ẹgbẹrun merin ilokasi eri ọrọ ti esin KIRIYO ati IMALE. Owo eyokan tẹlẹ 25s., nisisiyi 12s. 6d. Owo ki o lọ nilẹ fun Alukurani Yoruba fi 12s. 6d. ati owo iwọn Nigeria 1s. Ghana 2s. ranse si BOLAJI AKEWUKEWE 32, Offin Road, Lagos Nigeria.

**Irohin Yoruba**

No. 718. LAGOS, MARCH 8—MARCH 14, 1959. Kobo Meji (2d.)

**OWE**

"Ki iku ma pa ọsu, k'a ri ohun fi ka ọdun"
"Agbalagba ti o ba tẹlẹ tutu o ni lati kokọ da omi siwaju."

# AWOLỌWỌ ṢE ỌJỌ IBI ADỌTA ỌDUN

## Ijọba ni Dọkita Nimbẹ ko gbọdọ daṣa fifi ẹnikan jọba l'Eko

NI ọjọ Eti ti iṣe ọjọ kẹfa oṣu yi ni Olori Ọlọpa Ọgbẹni A. S. E. Agbabiaka mu Dọkita Ibiyinka Ọlọrun Nimbẹ ti o ti fi igbakan jẹ Mayọ l'Eko wa si iwaju Adajọ Kotu Kekere kan l'Eko pe o ngmura silẹ lati fi Ọmọ-ọba Kafaru Oluyẹ Dosunmu jẹ Oba Eko, o si je ohun ti o le da ọtẹ silẹ ninu ilu. Ninu ifẹjosun rẹ, Ọgbẹni Agbabiaka ti iṣe Oga Olọpa (Acting Deputy Commissioner of Police) ni gẹgẹbi aye iṣe on, on ni lati mojuto alafia ilu Eko.

O ni ni ọjọ kejila oṣu kejila odun ti o kọja lọ yi ti on gbọ irohin ohun ti Dokita Nimbe fe se yi ni on pe e (Nimbe) ati Ọgbẹni B. K. Anibaba wa sile iṣẹ on, o ni on so fun won pe on gbọ pe nwọn gbero lati je Oba si Eko.

Dọkita Nimbẹ gba pe bẹẹ ni, o si tun fi kun un pe awọn ẹgbẹ oselu on ni o ti yan Ọmọ-ọba Kafaru Oluyẹ Dosunmu lati fi i jẹ Ọba Dosunmu Keji ti Eko, o si tun se alaye pe Ọba Dosunmu Keji ni yio gba Ijọba lọwọ Ijọba Gẹẹsi.

Dokita Nimbẹ tun sọ wipe gbogbo eto igba-ade ti awọn fẹ ṣe fun Ọmọ-ọba Dosunmu na ninu Iga Idunganran ni awọn yio ṣe e, bi o tilẹ jẹ pe ibẹ ni Ọba Adele wa, awọn yio fi agbara wọ Iga na. Ọgbẹni Agbabiaka ni on kilọ fun Dokita Nimbẹ ki o maṣe ṣe bẹ ẹ, on si tun sọ nipa ọran na fun Minista Alamojuto Eto Ijoba Eko. Alamojuto na si kilọ fun un pe on ko gbodo gbọ pe nwọn ṣe eto ijoye kan ati wipe ki nwọn pa alafia ilu mọ fun oṣu meta.

Lẹhinna nigbati o tun di ọjọ kejila oṣu keji odun yi ni Dọkita Nimbẹ tun kọwe si Gomina Agba Apapọ Ijọba Naijiria pe ọjọ keje oṣu yi ni awọn yan fun ọjọ igbade na. Agbabiaka si sọ wipe bi igbade yi ba ṣẹlẹ, ọpọlọpọ alafia ilu ni nwọn o baje.

Lọya Nimbẹ, Ọgbẹni Balogun wa a bere pe tani Ọba Eko nisinyin gan an. Agbabiaka si dahun pe Ọba'birin Gẹẹsi (Her Majesty the Queen) Ọgbẹni Balogun ni bi Dọkita Nimbẹ ko ba fi agbara wọ iga nkọ? Agbabiaka si dalohun pe on mọ wipe Oba kan wa ni Iga, ko si ti si aṣẹ Ijọba lati mu u kuro nibẹ, nitorina on ki yio je ki ẹnikeni lọ si itosi ibẹ.

(Wo oju ewe kejila)



Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ

* * *

**OLOYE Ọbafẹmi Awolọwọ, Alakoso Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun Naijiria bẹrẹ ajọyọ ọjọ-ibi adọta ọdun rẹ pẹlu isin ọpẹ ninu Ile-Ọlọrun Ijọ Methodist Ikenne ni ọjọ Ẹti ti iṣe ọjọ kẹfa osu yi. Ẹniti o se akanse isin ati adura pataki fun Oloye Awolọwọ ati awọn ẹbi rẹ ni Olori Ijọ Methodist, Ẹniowọ julọ Alufa E. J. Jones**

Ọba I. B. Akinyẹle, Olubadan Ibadan wa ninu ogunlọgọ awọn Ọlọla ati awọn Oloye pataki pataki ti o ba Oloye Awolọwọ lọ si ibi isin idupẹ na. O si to iṣẹju marundinladọta ki nwọn to pari isin ọpẹ na. Lẹhin ti nwọn pari isin na tan ni gbogbo awọn ogunlọgọ enia na si ba Oloye Awolọwọ lọ si ile pẹlu ilu iṣẹdalẹ gọẹdu.

Ninu awọn ti o ki Oloye Awolọwọ ku ori ire ni ọjọ na ni Ọgbẹni D. C. Osadebay ti iṣẹ Olori Ẹgbẹ Alatako Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Iwọ-Orun, o ni tọkantọkan ni mo fi ki ọ ku orire ti ajọyọ ọjọ-ibi adọta ọdun rẹ, adura mi si Ọlọrun ni wipe ki O da ẹmi rẹ si fun ọpọlọpọ ọdun ki a le gbadun iṣẹ rere rẹ ti o se fun Naijiria.

Bẹẹna ni Dokita K. O. Mbadiwe, Olori Ẹgbẹ DPNC ki Oloye Obafemi Awolowo, ku orire. Ọgbẹni F. G. Ikoku ti ise [illegible] Alatako Igbimọ Ijọba Ipinlẹ Ila-Orun ki Oloye Ọbafẹmi Awolọwọ ku ori ire, o si tun sọ siwaju ninu ọrọ ikini ku ori ire na pe: eto iṣelu Naijiria lati ọdun 1951 mu idagbasoke wa pupọ, eyiti Oloye Awolọwọ ṣe ninu eto na ni o pọ. On ati awọn ẹlẹgbẹ rẹ ni o fi ero arojinlẹ ati lakaye ti o peye ja fun Ominira Ijọba Apapọ Naijiria ati eto iṣelu fun Apapọ Naijiria ti o peye pẹlu. Nipa iwa ki a duro gbọingbọin ni idi otọ ti Oloye Awolọwọ fi nja fun eto ati idera awọn ara ilu ati fun awọn ẹya ilu kekeeke ni Ipinlẹ ọtọ o mu ki Oloye Awolọwọ fi

(Wo oju ewe kejila)

## Eto iforukọ silẹ fun idibo l'Eko pari

EKO.

NI ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kini oṣu yi ni Ọgbẹni R. N. Rapson ṣe ikede pe gbogbo aropọ ẹkun mẹtẹta ti nwọn forukọsilẹ fun ibodidi l'Eko jẹ 146,280. Iye awọn ti o wa larin ilu Eko je 49,842; awọn ti Iha Ariwa ilu Eko je 48,081 ti iha Gusu Eko si jẹ 48,357. Ọgbẹni Rapson so wipe iwe eto gbogbo awọn ti o forukosile na l'Eko yio jade ni ọjọ kokanlelogun oṣu ti a wa ninu re yi. O ni esun ti onikaluku ba ni lori re nigbana ni awọn yio ṣe ayẹwo rẹ.

Ẹ wo Ayọrisi idije ere Bọlu ni oju ewe kejila

## Ọga ile-ẹkọ kan fi adọta pọun tan ọran ole jija

ỌYỌ.

NI ọjọ Iṣẹgun ti iṣe ọjọ kẹta oṣu yi ni Oloye Andrew Thomas, Adajọ Kotu Ibilẹ Ọyọ ṣe idajọ pe kiỌga Ile-ẹkọ Ṣọọṣ Aguda lu Awẹ kan, Joseph Oyeniyi, ẹni ọdun marundinladọta lọ fi adọta pọnun (£500) tanran si Kotu tabi ki o lọ si ẹwọn oṣu meta fun ẹsun pe, o ji iwe ede Oyinbo meji ti iye owo rẹ je ṣile mokanla (11s.) gbe ninu oṣu kejila ọdun ti o kọja yi.

Ẹjọ t' ọdaran na ro ni pe "Eṣu ni o tan on ti on fi ja ole na", ṣugbọn Adajọ sọ pe, on ko gbagbọ pe eṣu ni o tan an lọ jale ṣugbọn nitoripe o ti wa ninu iṣẹ olukọ ti pẹ ni on ṣe fun un ni anfani lati fi owo tan ọran na.

Ẹ wo irohin iku Ọlọla A. O. Ogedengbe ni oju ewe kẹfa

# nlanla ki Awolowo ku orire ojoibi Adota Odun

Nwon ni ireti pe Olorun yio jeki emi re o gun de ale ti Ipinle nla ti o nse Alakoso Ijoba re yio le je anfani ogbon itoni-sona ati iye re pe.

Mo f k ikini ti emi paapa kun un, ati ife pe, ki apere ogbon iselu re, ifarada re ati ti ilosiwaju ti o ni ninu ile Ijoba larin akoko die—paapajulo nigbati o ti di Olori Ijoba Ipinle Iwo-Orun Naijiria larin odun meje sehin yi. Ki Olorun ki o fun o ni opolopo odun ifaiyabale, alafia ati ti ariski lo.

Ki ogbon iselu re, aisinmi re ati wahala re lori awon enia e le je awoko fun awon ilu miran ti ko ni ifaiyabale to.

**Awon enia ja-nkan-ja-nkan wonyi lati ilu okere ati ni itosi bi Olola Lord Milverton, ti o ti je Gomina Ijoba Naijiria nigbakan ri; Ogbeni T. M. Shankland, Adele Gomina Ijoba Ipinle Iwo-Orun ni igbakan ri; Olola Chandos Hoskyns Abrahall, Gbakeji Gomina Ijoba Ipinle Iwo-Orun ni igbakan ri; Ogbeni Arthur Creech Jones, Asoju Ijoba Geesi fun awon ilu abe aabo Ijoba Geesi ni igbakan ri ati Eka Egbe Igbimo Awon Ilu Ominira ni Ilu Oba pelu ogunlogo awon enia fi iwe ikini ku orire ajoyo adota odun ojobi ranse si Oloye Obafemi Awolowo, Alakoso Ijoba Ipinle Iwo-Orun ni ojo ti o nse ojobi gangan.**

Olola **Lord Birdwood** ni:—
Inu mi dun pupo julo pelu awon ogunlogo enia lati ki Oloye Obafemi Awolowo, Alakoso Ijoba Ipinle Iwo-Orun Naijiria ku orire adota odun ojobi re.

Emi paapa ko ti i ni anfani lati be Iwo-Orun Naijiria wo, sugbon ninu ipade emi pelu Alakoso Ijoba Ipinle Iwo-Orun Naijiria na ni Londonu, mo mo dajudaju pe ni ori ipile tabi ore ti o fidimule dada larin ilu awa mejeji ni o ti nja fun anfani ilu re lehin ola. Eyi ni o fun mi ni ireti emi gigun ati arisiki fun Alakoso Ijoba Ipinle Iwo-Orun Naijiria na ati gbogbo awon ara ilu re pelu.

* * *

U.K. Branch of the Commonwealth Parliamentary Association ni:—
Awon Igbimo Iriju Eka Egbe "United Kingdom Branch of the Commonwealth Parliamentary Association ran mi lati ranse ikini ku orire atokanwa si Oloye Obafemi Awolowo, Alakoso Ijoba Ipinle Iwo-Orun Naijiria fun ajoyo adota odun ojobi re.

Awon Igbimo Iriju na mo ise ribiribi ti Alakoso Ijoba Ipinle Iwo-Orun na se fun Ipinle Iwo-Orun Naijiria ati fun awon Egbe Ominira Ijoba Geesi, nwon si gbadura pe ki Olorun fun un ni emi gigun ati alafia ara lenu ise re.

J. G. Lockhard
(Secretary)

* * *

Olola T. Chandos Hoskyns-Abrahall, Gbakeji Gomina Ijoba Ipinle Iwo-Orun ni igbakanri ni:—

Oloye Obafemi Awolowo nse adota odun ojobi re, mo si pelu awon ogunlogo ore re ki on ati awon ebi re pelu pe, nwon ku igbadun ajoyo ojobi na.

O ti wa ni aye ipo giga re yi fun odun pupo sehin lai fun ara re ni isinmi, o si ti bori oniruru isoro ti o wa ni ona re. Nitorina, nigbati Oloye Awolowo di eni adota odun yi, o di alagbara gidigidi nitori o ti ru eru isoro ti o wuwo pupo julo, o si da mi loju pe, o si tun ni ipinnu lati sa gbogbo agbara ti eda le sa lati fa Ipinle Iwo-Orun Naijiria ni teete de ona alafia ati oro. Mo gbadura pe ki Olorun fun un ni emi gigun ati alafia ara ati isegun ninu gbogbo ona re ninu awon odun ti o tun mbo.

**Ogbeni James Johnson MP., London:—**

Mo fi ife ododo ba Oloye Obafemi Awolowo, Alakoso Ijoba Ipinle Iwo-Orun yo ayo gidigidi fun adota odun ojobi re ti o nse, ki Oluwa fun un ni opolopo alafia ati aseyori ise se ninu awon odunrere ti o mbo yi fun Ipinle Iwo-Orun Naijiria.

Ki Olorun da emi re si ki o pe laiye lati le ma a tubo huwa omoluwabi si awon omo ilu re ni Afirika ati lati le tubo wulo fun won ninu ise iselu ti o nfi gbogbo ara se ti ododo ti ododo.

Mo fi t'okan-t'okan ki e.

* * *

**Omidan Margery Perham, Nuffield College, Oxford**

Inu mi dun lati ranse ayo si Oloye Obafemi Awolowo, Alakoso Ijoba Ipinle Iwo-Orun fun adota odun ti o da l'aiye ti o si nyo ayo re, mo

**Wo oju ewe kewa**






# Ilọrin ati Agbegbe rẹ ẹ dipo fun Ọpẹ

## Lati ọwọ Ọmọ-Ọba Adeniran Adefarakan, Eko

**OLOTU dakun gba mi laye lati kesi ọmọ Yoruba ilu Ilọrin ati agbegbe rẹ wipe, asiko ti a nwi de, adura mi si gbogbo ẹnyin aromọdọmọ Ọba Odudua ni wipe, ki Olodumare k'O jeki asiko na o de ba wa laiye pelu idunnu.**

Ohun ti o mu mi kesi ẹnyin enia mi na ni wipe, lati igbaiwaṣẹ ni Olodumare ti gbe iyi ati ola le Odudua ti o ṣẹ wa silẹ lowọ ati wipe lati igbana ni gbogbo ohun ti aromọdọmọ Odududa na ba da ọwọ le ni ṣiṣe ti nyọri si rere. Ninu igbesi aiye wa loni, Olodumare ti fi apẹrẹ iṣẹ ti Odudua ṣe ti o fi gba iyi ati ọla lowọ "Ọrẹ" ati "Oriṣanla" han wa, awọn ti Olodumare fi rọpọ 'Ọrẹ" ati 'Oriṣanla" lode oni yi ni awọn Ẹgbẹ Olomi ati Ẹgbẹ Alakukọ, ko si ohun ti o le yi wọn pada mọ, nitoripe "Iṣ o ti ṣe wa ni akọkọ ṣe, beni yio si ma wa titi lailai" ni Olọrun sọ ọ sinu Bibeli Mimọ.

Itan bi Olodumare ti ṣe gba ola ati iyi lowọ "Ọrẹ" ati "Oriṣanla" lọ ni nwọn ba ṣoki bayi :— Nigba-iwaṣẹ, "Ọrẹ" ni Olodumare kọkọ ran wa sile aiye, lẹhin ti o ti fi omi pe ile aiye rẹ, nigbati "Ọrẹ" dele aiye, o ba omi, kosi oke beni kosi ilẹ, ori omi na ni "Ọrẹ" te ẹni rẹ si gẹgẹbi agbara ti Olodumare tun ran "Oriṣanla"wa ba a nibẹ. Nigbati "Oriṣanla de ba "Ọrẹ" lori omi ni alai ko ṣe iṣẹ kankan, o bere lowọ "Ọrẹ" wipe, ewo ni ohun ti o mu ṣe ninu iṣẹ ti Olodumare ran o wa ṣe? "Ọrẹ" ko ri ohun kan pataki ṣe fun un, "Oriṣanla" so fun un wipe, iṣẹ ti Olodumare ran on wa ṣe nile aiye ni pe, ki o so omi yi di oke, ki eweko ati oniruru igi ti nso eso rere ma a hu jade ninu rẹ fun lilo ati fun anfani wa.

Nigbati "Oriṣanla" bẹrẹ iṣẹ tirẹ, o so diẹ ninu omi na di ilẹ. Eweko ti o kọkọ hu jade lori ilẹ na ni Igi-Ọpẹ. Nigbati ọpẹ yi dagba, o jẹ ohun ti o wulo fun wọn, nwọn njẹ, nwọn ngmu. Lara ọpẹ kanna yi ni nwọn nfi nkọ ile, lara ope igi na ni nwon fi se ẹni ti nwọn fi nsun, ninu re ni nwon fi i ṣe igi idana. Igi-opẹ yi wulo fun wọn depo ti okan wọn fi bale ninu ohunkohun, sugbọn iwa odalẹ ti awọn mejeji nhu si ara wọn, ko jeki nwọn o le ṣe iṣẹ ti Olodumare ran wọn ni aṣeyọri.

Nigbati Olodumare ri i wipe iwa ọdalẹ ti awọn mejeji nhu si ara wọn, ko jeki nwọn o le ṣe iṣẹ ti On ran wọn ti aṣeyọri, o ran Odudua wa ba wọn. Ni ọjọ ti Odudua yio rọ wa sile aiye, ori okuta kekere kan ti o wa ninu iṣẹ ti "Oriṣanla" ṣe ni o rọ si (eyi ni wipe, a ko bi Odudua, beni, ki iṣe wipe o ku, ẹsẹ ara rẹ lo fi rin wa, ẹsẹ ara rẹ lo fi rin jade kuro ni Ile-Ife. Ni asoye itan yi, mo gba ẹnyin onkawe ni iyanju ẹ ṣa ma a ka "Irohin Yoruba" yi dede. Bi Oluwa ba fẹ ni aipẹ ọjọ ni ẹ o ri itan na ka ni ẹkun rẹrẹ.

Nigbati Odudua dele aiye, o ba "Ọrẹ" ati "Oriṣanla" pelu iwa odalẹ wọn, o si bere iṣẹ ti Olodumare ran an wa ṣe, loriotitọ inu ati iwa aiko mọ t'ara ẹni nikan, werewere ni Odudua ti pari iṣẹ tirẹ ati eyiti awọn aṣiwaju rẹ ti ṣe ni aṣeti. Lati igbana ni Olodumare ti gbe ola ati iyi le Odudua lowọ, eyiti o fi jẹ wipe kosi ohun ti Odududa ati awọn aromọdọmọ rẹ yio da ọwọ le ni ṣiṣe ti nkan na ko ni yọri si rere titi di oni oloni.

### KẸ DIBO FUN ỌPẸ

Nipataki ọrọ mi, ko si ẹgbẹ oṣelu kan ti o to gbẹkẹle ninu ile awọn baba nla wa yi, bikoṣe Iran Ọmọ Odudua Ẹgbẹ Olọpẹ. **Action Group** awọn ni ẹgbẹ ti o nfẹ ọmọ ẹnikeji wọn fẹ rere, nitoripe Olodumare ti gbe iyi, ọla ati aṣeyọri iṣẹ baba nla wọn le wọn lowọ, kosi si ẹda kan ti o tun le yi i pada mọ, a jẹ Iṣu Ẹgbodo ni Ẹgbẹ Alakukọ ati Ẹgbẹ Olomi, nwọn nwa eni're fi kun ara wọn ni.

Iṣẹ rere wo ni ẹ ri ti Ẹgbẹ Olomi ṣe yori ri, tabi Ẹgbẹ Alakukọ ni yio tẹṣẹ bọ ilu kan ti ilu na ko ni bajẹ? Sardauna Sokoto ti mura tan lati kuro l'oko-ẹru, kiniṣe ti ẹnyin na ko ni jijadu lati bọ okun ajaga ti Hausa ju si nyin lorun sile? Teletele ni awọn Hausa ti nf'oju le nyin, ẹnyin funra ara nyin ni ẹ ko mojumora, nigbati enia ngmura lati wọnu ile kan, ti o ri enia bi mewa tabi ju bẹ ẹ lọ ti nwọn duro pelu ami ona ko dara ti nwọn de ẹ ni Fila, kini oluwarẹ tun nwa lọdọ iru ẹni bẹ ẹ?

Ẹ pada sẹhin, ẹ maṣe fi ara nyin j'oye a le e ko lọ, ẹ pada, ẹ wa dibo ti o mbọ yi fun awọn ọmọ iya ati ọmọ baba nyin. Awọn ni nwọn mọ ohun t'o tọ si nyin, ẹni ti o ba mọ oriki idile ẹni ni i mọ iyi ẹni. E dibo fun Ẹgbẹ Ọlọpẹ, ki owo iṣẹ nyin o le to nyin na, ki idọti oju ona oye ma ba nyin ni aṣọ jẹ, ki awọn ọmọ nyin o le ni ẹkọ-ofẹ, ki awọn agbalagba ti ko mọ iwe ka, ti nwọn ko mo o ko ki nwọn o le ri onisowo pataki ba sowo pọ, ki oniṣọwọ o le ri tirẹ ṣe.

Kosi ẹni to le'ri anfani nla ti Ẹgbẹ Ọlọpẹ ti ṣe kakiri ilu ti oluwarẹ tun jẹ sunmọ Ẹgbẹ Olomi tabi Ẹgbẹ Aladiẹ. Asiko anfani ti nyin lo sunmọ tosi yi, ẹ parapọ ẹ dibo fun Ẹgbẹ Ọlọpẹ ki idẹra o le de ba nyin .




# Ijọba Ibilẹ Eko ko fi kun owo-omi mọ

EKO,

NINU Ipade Igbimọ Ijọba Ibilẹ Eko ti nwọn ṣe ni ọjọ 'Ru ti iṣe ọjọ kẹdọgbọn oṣu ti o kọja yi ni nwọn yi ipinnu ti nwọn ti ṣe laipẹ yi pada. Ipinnu nwọn ti ṣe ri na ni pe nwọn yio fi sile meji lori ponun kookan owo-omi, nitori inawo ile-iwe ọfẹ wọ wọn lorun.



OLOYE A. O. LAWSON

* * *

Ṣugbọn lẹhin ti nwọn tun ro o sọtun-ṣosi wipe owo omi na a tu mbọ ma fun awọn ara ilu lati san ni nwọn ba pinnu pe awọn a kuku din inawo ti awọn ngna lori awọn Olori Igbimọ awọn ku. Nwọn mu ọọdun ponun (£200) owo ti nwọn nsan fun alaga wọn, Oloye A. O. Lawson kuro, nwọn si tun ge £800 kuro ninu £1,8000 ti nwọn nsan lọdun kan fun Alaiyeluwa Adeniji Adele Keji Ọba Eko ti iṣe Olori Igbimọ na.



# ORIN MIMỌ TI A FẸRAN

**Lati Ọwọ E. Alabi Thompson**

SUGBON opin ohun gbogbo ku si dẹdẹ: Nitorina ki ẹnyin ki o wa li airekoja, ki ẹ si ma a ṣora ninu adura. —I Peter ori 4 ẹsẹ 7.

1. Kristian' ma' ti wa simi
   Maṣe l'ero irora
   Li arin ọta l'o wa
   Ma ṣora.

2. Ogun agbara okun
   T'a ko ri, nko 'ra won lọ
   Nwọn nṣọ ijafara rẹ
   Ma ṣora.

3. Wọ ihamọra t'orun
   Wọ l'ọsan ati l'oru
   Esu ba, o ndẹdẹ rẹ
   Ma ṣora.

4. Awọn t'o ṣẹgun ṣaju
   Nwọn nwo wa b'awa ti nja
   Nwọn nñ ohùn kan wipe
   Ma ṣora.

5. Gbọ b'Oluwa rẹ ti wi
   Eniti iwọ fẹran
   F'ọrọ rẹ si ọkan rẹ
   Ma ṣora.

6. Ma ṣora bi ẹnipe
   Nipa rẹ l'a le ṣẹgun
   Gbadura fun 'ranlọwọ
   Ma ṣora.

**ITAN ORIN NA**

Arabirin ti o kọ orin yi ni Challotte Elliott, ẹniti o ri idanwo pupọ ati wahala larin ebi,, ara ati ọrẹ, ṣugbọn o gbekele ore-ọfẹ Ọlọrun ti o lagbara ju ohun gbogbo lọ; nipa ṣiṣe bayi, o ri iranlọwọ pupọ, o ṣi pinnu lati ma a kọ orin oke yi ṣaju adura rẹ ni ọjọ kẹrin ọsẹ ti iṣe (Wednesday) nigbati o ba lọ si ile Ọlọrun lati lọ gbadura.

# *Alhaji Ọyọlọla bẹ Olotu wo*

NI ọjọ Abamẹta ti iṣe ọjọ kejidinlọgbọn oṣu ti o koja yi ni Alhaji Salami Oyolola, ti iṣe Aṣoju Iwe "Irohin Yoruba" ni Adjame Abdijan Cote Voure ati aburo rẹ Alfa Busari Olọjede bẹ Olotu Iwe "Irohin Yoruba" wo ni Ile-iṣẹ Itẹwe Amalgamated Press (of Nigeria) Limited, 5/7 Apongbon Street, Lagos.

Inu Olotu si dun lati ri wọn, lẹhin ti nwọn fi ọrọ jomitoro ọrọ tan, bi gbogbo nkán ti nlọ si nihin ati lọhun, lẹhin eyi ni Olotu wa mu wọn digbẹrẹ yika idi gbogbo ẹrọ ti nwọn fi nṣiṣẹ itẹwe **Irohin Yoruba** na, inu wọn si dun pupọ lati ri gbogbo ọrọ ti o fi han wọn na pẹlu alaye bi nwọn ti ṣe nṣiṣẹ.

## Nwọn fi Lemomu agba titun jẹ l'Eko



**Aworan yi ni ti igbati nwọn nwe lawani fun Alfa Mohamed Liadi Alade Ibrahim ni Mọṣalaṣi Jimọ Eko nigbati nwọn nfi jẹ Lemọmu-Agba Mọṣalaṣi Jimọ na ni ọjọ Aiku ti iṣe ọjọ kini oṣu yi Lemọmu-Agba titun yi jẹ ọmọ Lemọmu-Agba Ibrahiim ti Lẹmọmu-Agba Nola rọpo rẹ nigbati o ku. Lemọmu-Agba Nola na ni o ku ni ọjọ karun oṣu keji ọdun yi ki nwọn to wa jẹ Lemọmu-Agba titun yi rọpo rẹ. Oye a mori o.**


Sloans's da irora mi duro lẹsẹkẹsẹ!



Orun ati awọn ejika ndun mi. Nitorina ni mo fi lọ si ọdọ eniti o nta oogun. O ni ki nlo Sloan's. Mo ra igo kan mo si fi dle si awọn ibiti o gbe ndun mi. O san lesekẹsẹ. Oora gbigbona rẹ ti o gbadun si wọ inu irora na lọ, o si le e lọ. Lati isisiyi lọ ni ngo ma a fi nlo Sloan's da awọn ẹsanra ati'rora mi duro nigbagbogbo. Kini se ti iwọ na ko fi lo Sloan's pẹlu? Ra igo kan loni.

SLOAN'S LINIMENT
NPA IRORA

Awọn Enia ti i ma a ṣ'eto igba ti mbọ



A ma a mu Siga Embassy nigbagbogbo

1/6d. fun mẹwa

Siga Virginia eledidi - nidi ti o pẹtu l'ẹnu.

